*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n:*
*Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jínde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krístì, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àinípẹ̀kun. Àmín.*

Tí o bá gba àdúrà yìí látọkànwá, a bá ọ yọ̀, nítorí o ti di ọmọ Ọlọ́run báyìí (Jòhánù 1:12-13).

### Kílọ́ kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ, kí o lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!

*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

**DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL**
*~ À ń tan Ìhìnrere Káàrí Aiyé*

**www.divineliterature.org**
**www.doveletters.org**

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023

# Ọ̀rẹ́ tí ó Dára Jùlọ!

*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n:*
*Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jínde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krístì, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àinípẹ̀kun. Àmín.*

Tí o bá gba àdúrà yìí látọkànwá, a bá ọ yọ̀, nítorí o ti di ọmọ Ọlọ́run báyìí (Jòhánù 1:12-13).

Kílọ́ kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ, kí o lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!

*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL
~ À ń tan Ìhìnrere Káàrí Aiyé

www.divineliterature.org
www.doveletters.org

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023

Ọ̀rẹ́ tí ó Dára Jùlọ!

Ṣé àwọn ènìyàn ń fiyà jẹ ọ́, bi? Ṣé wọ́n ń ni ẹ́ lára, tàbí wọ́n ń kẹ́gàn rẹ? Ṣé wọ́n ti pa ọ́ tì? Ṣé àwọn ènìyàn ń dà ọ́, tàbí wọ́n ti já ọ jù sílẹ̀? Bóyá ẹnì kan tí o fẹ́ràn ti já ọ kulẹ̀, tàbí ó ṣe ohun tí ó dùn ọ́ wọnú egungun. Ó ṣeé ṣe pé, o dá wà; kò sì sí ẹnìkan láiyé tí o lè gbára lé láti dúró tì ọ́ nígbà ìṣòro.

Má ṣe banújẹ́! Krístì lóye gbogbo ohun tí ò ń là kọjá. Ó lóye ẹ̀dùn ọkàn rẹ. Krístì nírìírí ìṣòro ẹ̀dá-ènìyàn ní kikún, nígbà tí Ó wà lórí ilẹ̀-aiyé. Yàtọ̀ sí pé Jésù Krístì dá nìkan wà lọ́pọ̀ ìgbà, àwọn ènìyàn kẹ́gàn Rẹ̀ pẹ̀lú; wọ́n dà á, wọ́n ṣẹ̀sín Rẹ̀, wọ́n sọ̀rọ̀ nípa Rẹ̀ láìdáa, wọ́n sì da lóró gidi gan-an (Àìsáyà 53:3, 5, 7, 8).

Ọ̀rẹ́ dára láti ní, ṣùgbọ́n wọ́n lè má sí níbẹ̀ fún ọ ní gbogbo ìgbà. Kìí ṣe ohun ìyàlẹ́nu kí àwọn ọ̀rẹ́ máa já ni kulẹ̀ ní àkókò tí a nílò wọn jù. Bí àwọn kan ṣe jẹ́ onímọtara-ẹni-nìkan, bẹ́ẹ̀ ni àwọn mìíràn ní èrò rere, àmọ́ síbẹ̀, wọ́n ń já ni kulẹ̀. Àwọn mìíràn ní ọ̀pọ̀ ohun tí wọ́n ń ṣe fúnni bí ọ̀rẹ́; ṣùgbọ́n ohun tí wọ́n ń ṣe yìí lè mú àbámọ̀ àti ìyọnu wá níkẹyìn.

Jésù Krístì ni Ọ̀rẹ́ kanṣoṣo tí o lè fi gbogbo ọkàn tán an. Ìbádọ́rẹ̀ẹ́ Rẹ̀ ń fúnni ní ayọ̀ tí kò lópin, àlàáfíà, àti ọ̀pọ̀ ìbùkún. Òun ni Ọ̀rẹ́ tó nífẹ̀ẹ́, tí ń fà mọ́ àwọn ọ̀rẹ́ Rẹ̀ tímọ́tímọ́ ju ẹnikẹ́ni lọ (Òwe 18:24).

Krístì pe gbogbo àwọn tí wọ́n wà ní ipò ìbátan pẹ̀lú Rẹ̀ ní, *"Ọ̀rẹ́"* (Jòhánù 15:13-15). Ìfẹ́ tí Ó ní sí wọn ò láàlà, ó sì jinlẹ̀. Ó ń da ìfẹ́ Rẹ̀ sórí wọn, Ó sì ń dúró tì wọ́n gbágbáágbá lọ́jọ́ dídùn àti lọ́jọ́ kíkan. Ó ń ṣàárò wọn tí wọ́n bá rìn kúrò lọ́dọ̀ Rẹ̀ - kò fẹ́ pàdánù wọn rárá (Mátíù 18:11-13). Ó ń bẹ̀bẹ̀ fún wọn lọ́dọ̀ Ọlọ́run Bàbá, pẹ̀lú (1 Jòhánù 2:1). Èyí túmọ̀ sí pé, o lè bá Jésù Krístì sọ ohunkóhun: yálà ìṣòro tí o ní, ẹ̀dùn ọkàn rẹ, tàbí àìlera yòówù tí ò ń dojúkọ; ìwọ yóò sì rí ìtùnú gbà láti ọ̀dọ̀ Rẹ̀ - èyí tí ọ̀rẹ́ aiyé kankan kò lè fún ọ. Wo irú Ọ̀rẹ́ Àgbàyanu tí Jésù Krístì jẹ́!

Krístì ṣe ìlérí láti fún gbogbo àwọn tí ó ní wàhálà ní ìsinmi, bí wọ́n bá wá sí ọ̀dọ̀ Rẹ̀ (Mátíù 11:28-30). Ó wù ú kí o jẹ́ Ọ̀rẹ́ Rẹ̀, ṣùgbọ́n o gbọ́dọ̀ kọ́kọ́ wá ìbátan pẹ̀lú Rẹ̀. Kì í ṣe ohun tí ó le rárá, bóo ṣe rò, láti jẹ́ ọ̀rẹ́ Krístì. Ìwọ yóò bẹ̀rẹ̀ síí jẹ àwọn àǹfààní ìbádọ́rẹ̀ẹ́ Rẹ̀ ní kété tí o bá ti gbà á gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà rẹ, tí o sì pinnu láti máa ṣe ìfẹ́ Ọlọ́run Bàbá (Jòhánù 15:14). Àyè ṣí sílẹ̀ fún ọ báyìí láti jẹ́ ọ̀rẹ́ Rẹ̀. Jọ̀wọ́ aiyé rẹ fún un lónìí!

## Báwo ni a ṣe lè gba Jésù Krístì nísinsìnyí?

*Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Romu 10:9).*

1. Gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́.
2. Ṣe ìpinnu láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.
3. Gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Jésù Krístì kú fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ lórí igi àgbélébùú, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú.
4. Lẹ́yìn náà, tẹ orí rẹ ba, kí o gba àdúrà yìí.


Ṣé àwọn ènìyàn ń fiyà jẹ ọ́, bi? Ṣé wọ́n ń ni ẹ́ lára, tàbí wọ́n ń kẹ́gàn rẹ? Ṣé wọ́n ti pa ọ́ tì? Ṣé àwọn ènìyàn ń dà ọ́, tàbí wọ́n ti já ọ jù sílẹ̀? Bóyá ẹnì kan tí o fẹ́ràn ti já ọ kulẹ̀, tàbí ó ṣe ohun tí ó dùn ọ́ wọnú egungun. Ó ṣeé ṣe pé, o dá wà; kò sì sí ẹnìkan láiyé tí o lè gbára lé láti dúró tì ọ́ nígbà ìṣòro.

Má ṣe banújẹ́! Krístì lóye gbogbo ohun tí ò ń là kọjá. Ó lóye ẹ̀dùn ọkàn rẹ. Krístì nírìírí ìṣòro ẹ̀dá-ènìyàn ní kikún, nígbà tí Ó wà lórí ilẹ̀-aiyé. Yàtọ̀ sí pé Jésù Krístì dá nìkan wà lọ́pọ̀ ìgbà, àwọn ènìyàn kẹ́gàn Rẹ̀ pẹ̀lú; wọ́n dà á, wọ́n ṣẹ̀sín Rẹ̀, wọ́n sọ̀rọ̀ nípa Rẹ̀ láìdáa, wọ́n sì da lóró gidi gan-an (Àìsáyà 53:3, 5, 7, 8).

Ọ̀rẹ́ dára láti ní, ṣùgbọ́n wọ́n lè má sí níbẹ̀ fún ọ ní gbogbo ìgbà. Kìí ṣe ohun ìyàlẹ́nu kí àwọn ọ̀rẹ́ máa já ni kulẹ̀ ní àkókò tí a nílò wọn jù. Bí àwọn kan ṣe jẹ́ onímọtara-ẹni-nìkan, bẹ́ẹ̀ ni àwọn mìíràn ní èrò rere, àmọ́ síbẹ̀, wọ́n ń já ni kulẹ̀. Àwọn mìíràn ní ọ̀pọ̀ ohun tí wọ́n ń ṣe fúnni bí ọ̀rẹ́; ṣùgbọ́n ohun tí wọ́n ń ṣe yìí lè mú àbámọ̀ àti ìyọnu wá níkẹyìn.

Jésù Krístì ni Ọ̀rẹ́ kanṣoṣo tí o lè fi gbogbo ọkàn tán an. Ìbádọ́rẹ̀ẹ́ Rẹ̀ ń fúnni ní ayọ̀ tí kò lópin, àlàáfíà, àti ọ̀pọ̀ ìbùkún. Òun ni Ọ̀rẹ́ tó nífẹ̀ẹ́, tí ń fà mọ́ àwọn ọ̀rẹ́ Rẹ̀ tímọ́tímọ́ ju ẹnikẹ́ni lọ (Òwe 18:24).

Krístì pe gbogbo àwọn tí wọ́n wà ní ipò ìbátan pẹ̀lú Rẹ̀ ní, *"Ọ̀rẹ́"* (Jòhánù 15:13-15). Ìfẹ́ tí Ó ní sí wọn ò láàlà, ó sì jinlẹ̀. Ó ń da ìfẹ́ Rẹ̀ sórí wọn, Ó sì ń dúró tì wọ́n gbágbáágbá lọ́jọ́ dídùn àti lọ́jọ́ kíkan. Ó ń ṣàárò wọn tí wọ́n bá rìn kúrò lọ́dọ̀ Rẹ̀ - kò fẹ́ pàdánù wọn rárá (Mátíù 18:11-13). Ó ń bẹ̀bẹ̀ fún wọn lọ́dọ̀ Ọlọ́run Bàbá, pẹ̀lú (1 Jòhánù 2:1). Èyí túmọ̀ sí pé, o lè bá Jésù Krístì sọ ohunkóhun: yálà ìṣòro tí o ní, ẹ̀dùn ọkàn rẹ, tàbí àìlera yòówù tí ò ń dojúkọ; ìwọ yóò sì rí ìtùnú gbà láti ọ̀dọ̀ Rẹ̀ - èyí tí ọ̀rẹ́ aiyé kankan kò lè fún ọ. Wo irú Ọ̀rẹ́ Àgbàyanu tí Jésù Krístì jẹ́!

Krístì ṣe ìlérí láti fún gbogbo àwọn tí ó ní wàhálà ní ìsinmi, bí wọ́n bá wá sí ọ̀dọ̀ Rẹ̀ (Mátíù 11:28-30). Ó wù ú kí o jẹ́ Ọ̀rẹ́ Rẹ̀, ṣùgbọ́n o gbọ́dọ̀ kọ́kọ́ wá ìbátan pẹ̀lú Rẹ̀. Kì í ṣe ohun tí ó le rárá, bóo ṣe rò, láti jẹ́ ọ̀rẹ́ Krístì. Ìwọ yóò bẹ̀rẹ̀ síí jẹ àwọn àǹfààní ìbádọ́rẹ̀ẹ́ Rẹ̀ ní kété tí o bá ti gbà á gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà rẹ, tí o sì pinnu láti máa ṣe ìfẹ́ Ọlọ́run Bàbá (Jòhánù 15:14). Àyè ṣí sílẹ̀ fún ọ báyìí láti jẹ́ ọ̀rẹ́ Rẹ̀. Jọ̀wọ́ aiyé rẹ fún un lónìí!

## Báwo ni a ṣe lè gba Jésù Krístì nísinsìnyí?

*Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Romu 10:9).*

1. Gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́.
2. Ṣe ìpinnu láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.
3. Gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Jésù Krístì kú fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ lórí igi àgbélébùú, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú.
4. Lẹ́yìn náà, tẹ orí rẹ ba, kí o gba àdúrà yìí.